# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

V L XIV 858 LAGOS SRATUDAY FEBRUARY 23rd — MARCH 1st 1963 KỌBỌ MEJI (2D)

**Ki A Ma Ri:**

# "Ote Imale Ta Ju Koko" Tun Fe Be Sile Ni Ilu Eko

## Awon Imale Pe Ara Won Lejo Si Kotu

EKO – Ọrọ ni yio sọra ẹ! o da bi ẹni pe nkan ti o da ọrọ "Imale ta j u Koko (cocoa) l ọ" silẹ nilu Eko ni iwọn ikan bi ogoji ọdun sẹhin tun fẹ bẹ silẹ larin awọn janma Imale Eko, Itumọ ọrọ "Imale ta ju koko ti awọn sọ nigbana ni wipe awọn Imale dun ba sẹjọ nitoripe wọn rọ pupọ.

Asiko ti a wi yi ni awọn Imale Eko nṣe ejọ lori Mọsalasi nla (Mọsalasi Jimọ) l'Eko; igbana ni nwọn kọ orin wipe "A gba kọkọrọ, a gba wutuba ọwọ w a tẹ nkan nla loni."

Ni ti otitọ, gbogbo awọn ọmọ ti a bi lasiko igbana lo ti di baba loni. Lẹhin ẹjọ ti Mọsalaṣi Jimọh yi ni ọtẹ Esugbayi Eleko ati ọtẹ Balogun ilu. Ko si ẹni ti o ba mọ itan awọn ọtẹ nwọnyi ti yio tun fẹ ki iru wọn tun bẹ silẹ lasiko ti a wa yi.

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)

# Oloye Biney Jalaisi

YABA—Irohin kan wa ni oru ana wipe Oloye W. H. Biney, ẹniti o kọkọ bẹrẹ iṣẹ a-npe-alaru-fọkọ l'ebute Eko jalaisi ninu ile rẹ ni Suru-Lere lana. Ẹni ọdun mẹtadinlọgọrin ni, o si fi ọmọ mẹrin saiye.

Ni ọdun 1911 ni o fi ilu rẹ (Gold Coast) silẹ ti o wa fi ijoko si ilẹ Nigeria nibi.

# OBITUARY

We regret to announce tee death of Chief W.H. Biney (well known ship chandler) which sad event took place last night in his Suru Lere residence at the age of 77.

The late Chief came to Nigeria from Gold Coast in 1911. He is survived by four children among whom is a young barrister. Mr. Kweku Biney. A member of Lagos Race Club, deceased was also horse owner.

## LAGOS RACE CLUB

FEBRUARY MEETING 1963

NOTICE OF ADJUSTMENT RACING CALENDAR

There will be no Race Meeting on Saturday 2nd March, 1963 and the Third Day Racing scheduled for that day will take place on Tuesday 26th February, 1963.

The last day racing will take place on Saturday 9th March, 1963 as scheduled.

I. A. S. Adewale
Chairman
LAGOS RACE CLUB

**Enmo De!**

# Awon Ole Nwa Ori-Oku Ni Majidun

ABULE MAJIDUN (leti IKORODU)—Nibiti ẹlẹkun gbe nsọkun ni awọn ala-yọ nyọ; awọn ọmọ jaguda dapọ mọ awọn ọlọṣa dana-dana ti nwọn ma npiyẹ loju ọna mọto Ikorodu mọ Shagamu ti wa si Majidun nibi lọsẹ yi lati ma wa "burọda pẹlu anti wa ti ti o pade agbako iku mọto nibi" ni nwọn sọ wipe awọn nwa, a jẹ ori-oku pẹlu ẹru ni nwọn nwa lati ji ko.

Onirohin Eleti-Ọfẹ ni gbara ti awọn arabi na ti de Majidun ni nwọn ti lọ sọdọ awọn ọlọkọ apẹja ibẹ wipe awọn ni enia ninu awọn ti mọto akẹru da somi awọn si tẹ ya ọkọ wọn lati fi wa oku awọn anti awọn na.

Nkan ti o jẹ iyanu ọrọ wọn ni wipe nwọn ko wa lojumọmọ nigbati olukuluku nri oju ara wọn, n ọn gbe ina tọṣilaiti (torch light) to mẹfa ti nwọn si lagbara lọwọ.

(Wo iyoku loju ewe keji)

# Barika De Salla!



OLOYE ABUDU YE-KINI OJIKUTU, BALOGUN Ilu EKO ki gbogbo enyin Musulumi agbaiye jake jado wipe e ku ewu alaja odun Awe, ki Oluwa Olodumare jowo se odun na ni odun elemi gigun ati alafia ara odun owo tabua, odun omo titun ati odun ifokan balę fun gbogbo ara ilu patapata.

"Ti a ba ro iye awon ti a jo bere AWE yi ti a ko si pari re loju won, pelu oro awon ▪ ko se amodi rara ti nwon ku iku ojiji, a ko le se alai darin ayo fun Oluwa ti o da wa si di ojo oni.

"Eyi na ni o mu wa ranti nigbati awa Yoruba ba nse aisun eye igbeyawo ti o ba di oganjo oru ti iya-ilu ndun kan-kan-kan, oro orin kan ti o lo bayi :

Lawu erebe, erebe la-
wu 2ce, Awa ko rohun
f'ayo a fope lo ye wa o,
Lawu erebe.

"Nje ko wa tope ati ayo fun awa ti Olorun da si dojo oni ? Ni ikehin adura mi, Oluwa ko se odun na ni abo odun ko si je ki emi se opo re

"To your readers who cannot read Yoruba literature properly, I say may the kindness and blessing of Allah, peace, love, and harmony with all their happy trains abide with each and every one of us now and forever more. Amen

BARIKA DE SALLA."

## Awon Ole Nwa Ori Oku Ni Majidun

(O bere loju ewe kinni)

Okan ninu awon oloko ti o nwa won ni oro ti on gbo lenu won ni o jeki on mo wipe ori-oku ati owoti awon oku ti mo tobi won ni awon olosa na nwa kiri lati ja gbe nitorina on ko fi tara tara ba won wa oku ni isale omi loru oganjo fun awon ti o fe f'ori oku gun ose aware.

O to oku meriadin-logua nisisiyi ti awon ara Iperu ati awon ara Odeti enia won ku sinu odo Majidun na ti ri gbe nisisiyi.

BARIKA DE SALA!
E ku odun Awe.



Aworan yi ni ti Oba Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji, Ologbon dori eja mu, Adeniji Adele omo Buraimo. E wo oju ewe karun iwe yi fun oro alajobi ti oba na fi ki gbogbo enyin Musulumi Eko ku odun itunu Awe ti a fe se lola yi.

## Oloye Oluwa Ki Awon Musulumi Eko Ku Odun Awe

Oloye Abdul Rasheed Afuwape Oluwa, Oloye Oluwa tuntun ni on ki gbogbo awon Musulumi ilu Eko, Ebute Metta ati awon ara wa ti nwon ko lo si Eko-tuntun ni Suru-Lere pe nwon ku ipalemo odun isinu Awe ti a o se ni otunla

Awon agbalagba ni odun ni a ma fi nyin odun, iyen ni odun ti odun ni ; odun na dara pupo (a ko gbodo wi nkan miran) sugbon awa ti Allah dasi di ojo oni, o ye ki ayo, ki a si se ope fun un.

(Wo yoku loju ewe kejo)

# Olopa "Dadi Alaja" Mbo Wa Nigeria

LONDON—A gbo irohin pe Ogbeni Olopa Oyinbo kan ti o je wipe aja ni on fi nmu awon arufin ti mbo wa si Nigeria ni aipe yi lati wa ko awon olopa wa lona ti nwon yio fi ma lo awon aja lati ma awon ole ti nwon ba ya ehanna.

Oruko olopa "dadi alaja" na ni o nje Peter Stephenson, eni odun mejidinlogbon ni, ilu ti nwon npe ni Middlesbrough ni o wa ni ilu Oyinbo ti o nse ise olopa alaja t're lowo nisiyi.

Ti Ogbeni olopa alaja na ba de ninu osu ti a fe bo si yi, ose meta ni yio se ki o to ko die ninu awon omo wa ti o nse ise olopa lo si ilu re lati lo ko nise bi nwon yio se ma lo awon aja lati ma fi mu awon arufin.

Ti o ba ti ko won ni 'se na tan, on na pelu iyawo re ati awon omo won meji mbo wa joko si Nigeria lati ma fi aja ko awon elegiri wa si iwaju awon adajo ki nwon to lo gba ewa ni egba ewon.

## Oloye Akintola Ni Ijoba On Si Ni Owo Lowo

EKO—Oloye S.L. Akintotola, Olotu Ijoba Ipinle Iwo Orun so abe niko fun gbogbo awon oniwe irohin agbaiye ninu ipade ti o ba won se ninu ile re ni Ajasa Street l'Eko ni ijeta. O ni o ya on lenu lati ma gbo kakiri ninu iwe ti awon onirohin na nte jade wipe ko si owo lowo Ijoba Ipinle awon mo ni Ibadan.

Oloye Akintola ni oro na ko ri be rara, o ni ogorun oke ponun si wa sandi lowo awon ti nkankan ko gun, adojo oke ponun miran si tun seku fun Ijoba awon. Ijoba Apapose l'Eko si tun se ileri owo miran ti o ni lati te awon lowo laipe yi fun awon gegebi iranlowo ti nwon nse fun awon Ijoba Ipinle miran.

Olotu Ijoba Ipinle Iwo Orun ni oda-owo ti awon Ijoba Ipinle miran le ju ti awon lo, o ni owo ti awon le na lori nkan aba ise nla ti awon ngbero lati se fun ilu ni ko si, ko nse eyiti awon le fi san owo awon osise Ijoba.

### Ise Duro

Oloye Akintola ni gere-bi ifihan iwadi adajo Coker opolopo awon ile ise ti ko ba pa owo wole fun Ijoba ni awon yio pare bi ogan ninu awon ajoda ise Ijoba (corporations) ti nwon se iwadi won ninu odun ti o koja. O ni awon yio wa ibikan fi oro awon ti ko ri ise se nilu si, nitoripe awon ko fe ki iya ise je enikan rara.

**E KU EWU ODUNAWE**

## Olofintoto Eleti-Ofe Nfi Oju Agba Wo

# Ọro Awon Osise Oko To Di Koko

### Jamba S'ole

Ọjọ buruku Eṣu fomi wẹ! Ọjọ ti oguulọgọ awọn oṣiṣẹ ti nwọn nko ẹru lebute ọkọ elefin ni Apapa, Eko, Warri, Sapẹlẹ ati Port-Harcourt da iṣẹ silẹ ti kọja, o si ti d itan nisisiyi, ṣugbọn emi OLOFINTOTO "Eleti-Ọfẹ" fẹ fi ẹnu pa ọrọ arinyanjiyan lariu awọn oṣiṣẹ na pelu awọn ọga alagbaṣe wọn niwọn iba ranpọ. Tabi ko dara bẹ?

Awọn Yoruba ni oju bọrọ kọ ni a fi ngba ọmọ inu ekurọ, iyẹn ni ọrọ awọn oṣiṣẹ na pẹlu awọn ọga ti o wa larin wọn pẹlu awọn Oyinbo ọlọkọ elefin ti nwọn ni ki nwọn ma ba awọn wa lebira ti yio ma ba awọn ko ẹru kuro ninu ọkọ ti ọkọ ba ti gun s'ebute tabi ti yio ma ba awọn ko ẹru sinu ọkọ ti o ba fẹ lọsi ilu Oyinbo.

Nigbati oju ko ti ja pupọ bi ti aiye isisiyi, awọn Kurumọ lati ilu ti a npe ni Liberia ni nwọn nko wa si Nigeria lati ma ba wọn ṣe iṣẹ bọyi Awọn Kurumọ na ni agbara pupọ, owo ọya ti nwọn si nsan fun wọn nigban ako pọ rara.

### Onile Taji

Boya ẹ le bere wipe kinni itumọ Kurumọ tabi orukọ ti awọn ara Monrovia ni Libẹria njẹ niyi ni tabi kilo faa ti nwọn fi npe wọn bẹ. Emi le dahun ibere yi. Awọn Oyinbo inu ọkọ lo npe wọn ni CREW, ti nwọn ba si fọ ede Oyinbo bi ẹnikan lere ninu wọn wipe iṣẹ kilo nṣe, a dahun bayi: I AM A CREWMAN; ibẹ ni awọn ti ko mọ idi ọrọ na ba fi npe wọn ni Kurumọ di ọjọ oni.

Bi awọn ọkunrin ti a npe ni Kurumọ yi ba ṣe iṣẹ ti Apapa ati ti ebute Eko tan, awọn ọlọkọ a tun ko wọn sinu ọkọ lọ si Port-Harcourt lati lọ ṣe iṣẹ a-nko ẹru yi nibikibi ti ọkọ elefin ti nwọn ba gba wọn fun ba nlọ. Awọn Oyinbo ọlọkọ yi ni nwọn si ni lati ma bọ wọn pẹlu onjẹ ni gbogbo igba ti nwọn ba mba wọn ṣe iṣẹ. Awọn ara wa yi si fẹran irẹsi (rice) pẹlu ẹran oniyọ gẹgẹbi onjẹ wọn pupọ. Awọn ti nwọn nṣiṣẹ fun kii si fii du wọn.

### Ise Biney

O to iwọn nkan bi ọdun mẹtalelogoji nisisiyi ti ẹnikan ninu awọn akọwe enia-dudu ti o mba awọn Oyinbo oniṣowo ṣe iṣẹ l'Ẹhingbẹti ju iṣẹ rẹ silẹ ti o ni on yio ma gba awọn lebira fun awọn Oyinbo ọlọkọ oju-omi. Ọgbẹni Biney lo kọkọ bẹrẹ iṣẹ a-npe-alaru-f'ọkọ ni ilu Eko.

Nigbati Ọgbẹni Biney bẹrẹ iṣẹ na, ko ya si ọdọ awọn Kurumọ, ọdọ awọn ara ilu Oke ti nwọn ngba'ru kakiri ni ita l'Eko ni o ni ki nwọn wa ṣiṣẹ ojumọ. Awọn ọkọ elefin ti o nde lati ilu Oyinbo ko wọpọ to ti isisiyi.

### "Afoke"

Nitorina lati ri awọn ara oke lati agbegbe Ilọrin kẹ wa s'Eko wa siṣẹ ko le tobẹ nitoripe ọpọlọpọ wọn ni nwọn gbọ irohin wipe "OWOMBẸ lẹsẹ ODO" ti nwọn si nfi owo ara wọn wọkọ wa s'Eko wa wọ iṣẹ a mba wọn wa ọkọ onigi lọ si Ẹpẹ, Ejinrin ati Agbadarigi.

Ti nwọn ba ndari bọ lati awọn ọja ti mo darukọ nwọnyi, nwọn a fi owo diẹ ra ẹni (native mat) ati ati gari wa si Eko lati ta; gbogbo igbati ọkọ oju omi ti nwọn nwa ko ba ti lọ sọja, nwọn a ma kiri gari bayi; "A-din-gbẹ gari o, jojo bi oloyọ lori, agbere loloyọ ngbe".

### Af'igbo

Ẹnu awọn ara wa lati ilu Oke yi dun fun orin kikọ lẹnu iṣẹ pupọ, nitorina awọn ara Eko fun wọn ni orukọ "AFOKE AFI GBO, E ṢẸNI ELE DURO". Nigbana nwọn ko ni ọkanjuwa, nwọn ki jale. Ko dabi aiye ti isisiyi ti gbogbo ara aiye ti di ọlọṣa.

Ma duro nihin lọsẹ yi, ṣugbọn ti o ba di ọsẹ ti mbọ ma sọ nkan ti o fa a ti nwọn ṣe da iṣẹ silẹ ati IWE WOSIKA ti iya ọkan ninu awọn oṣiṣẹ na kọ si i lati Ilọrin fun yin.

Ẹ Ku ipalẹmọ ọdun itunu Awẹ.

### Akiyesi

Ọrọ Ilu Togo ati Olympio wa ni oju ewe kẹfa iwe yi. Ẹ lọ ka a. Ti o ba fẹ mọ bi gbogbo nkan ti nlọ si ninu aiye ti a wa yi, ki o ma ka iwe rohin ELETI-ỌFẸ ni ọsọsẹ...OLOFINTOTO wa wa lati ṣe alaye bi ọrọ awọn oṣelu ti nlọ si fun nyin nipa ilẹ Nigeria, Ghana, Togo, Dahomey, Sierra Leone, Gambia ati kakiri agbaiye.

Owo iyebiye ni a si san fun onirohin ti o nfi wosika bi nkan ti nlọ si ni arin ilu Togo ati Ghana ranṣẹ si wa nisisiy, Eleti Ọfẹ ti d'araba, apa ọmọde ko ka.

# Nwon Si Ilekewu

## Tuntun Kan Ni Ilorin

ILỌRIN — Ilekewu tuntun kan ti awọn ẹgbe kan fi ẹgbẹdọgbọn pọnun (£5000) kọ si ilu Ilọrin ni a gbọ nwọn si laipẹ yi pẹlu aṣeyẹ atata. Ọba Ilọrin Alaam Sulu Gambari ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ti orukọ wọn njẹ ILỌRIN JEBUATUL HULAMAU pe wipe ki o wa ba awọn ṣi ile kewu tuntun na.

Ọba Ilọrin ni inu on dun pupọ ẹyẹ ati iyi ti awọn ọmọ ẹgbẹ ti nwọn kọ ilekewu na fun ti nwọn ni ki on wa ba wọn ṣi i. O ni inu on si tun mẹ ndun si nkankan, iyẹn ni ti awọn alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti ko fọwọ rọ ẹkọ kewu sẹhin,

O ni bi nwọn ti nsa agbara wipe ki awọn ọmọ Ariwa ma fa sẹhin ninu ẹkọ ti awọn Oloyinbo de, bẹni nwọn si nmojuto ẹkọ ni ọna ẹsin ti awọn Musulumi. Ọba Ilọrin ni ninu awọn ilu ti o jẹ pataki ninu ẹkọ kewu yi, Ilọrin jẹ ọkan nibẹ.

Adọrin ọmọ ilekewu ni nwọn Aṣẹṣẹ gba sibẹ. Ọba Ilọrin si ba wọn sọrọ iṣiri pupọ lọjọ na, o ni ki nwọn maṣe da oju ti awọn Alufa wọn, ki nwọn si koju si ẹkọ tiwọn ba nkọ wọn daradara.

### Oba Ilorin

Ki Ọba Ilọrin to kuro nibi aṣeyẹ iṣile ọjọ na; awọn ọmọ ẹgbẹ ti o kọ ilekewu na fi iwe Korani nla kan taa lọrẹ wipe ki o le ma fi niran ọjọ ti o ba awọn ṣi ilekewa na. Diẹ ti a le da ninu orukọ awọn ọmọ ẹgbẹ na niyi, Alhaji Kasali, Alhaji Abudu Karimu Agaka, Alufa Isola Agbabiaka, Alufa Salawu Oloyin, Alufa Adamu Idiadan ati Ala Salihu Ayinde.



# Barika

## De Sala!

Alhaji Maitama Sule alamojuto eto nkan isura ilẹ ati agbara fun Ijọba Apapọ l'Eko Minisita yi ni o fẹ jẹ wipe on ni o kere ju ninu gbogbo awọn Minisita wa, o ni on ki gbogbo Imale kakari ilẹ Nigeria nwọn ku ipalẹmọ ọdun Awẹ ti yio pari ni Ọla.

# ELETI–OFE

A NJUWON KO ṢE WI LEJO

EDITORAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI—OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XIV. NO. 857 SATURDAY FEB. 23— MARCH. 1 1963


# Inu Wa Dun

ETI ti o ba gbọ a–lọ–re ni o ni lati gbọ abọ–re ; inu awa oniwe "Eleti–Ọfẹ" dun pupọ lati sọ fun ẹnyin ti ẹ nkawe irohin wa na jake-do ilẹ Nigeria, Dahomey, Togo, Ghana ati awọn ilu okere miran wipe ọrọ wa ti a nsọ lemọ lemọ lori gbogbo awọn enia ti nwọn fi igba kan ka, ti nwọn ko le gbe iyọri rẹ jade, ti a si ṣi awọn Olotu Ijọba wa leti wipe ki nwọn tun wa ka n i o b a oju mu, ko jẹ lasan : Irohin ti a gbọ ninu ọsẹ yi ni wipe awọn alakoso Ijọba wa ti fi ọwọ si i wipe ki nwọn tun gbogbo wa ka lọkọkan ati ọmọ ọwọ ati arugbo.

NIGBAYI ni awa ri pe awọn Alakoso Ijọba wa ko fẹ f'ọbọ lọwa lori ọrọ enia kika na nitoripe ko si ẹnikẹni to fi ọkau tan wọn lori ayọrisi enia ti nwọn ka na ti nwọn fẹ gbe si ita.

## Ariwo Po

ARIWO lo pọ ole ko fẹ ju nkan ọwọ rẹ silẹ. Bi ẹnyin ọkawe wa paapa ba ṣe ranti ẹ o ri wipe ọpọlọpọ yin ni o kigbe titi lori awọn ti o fẹ ko ọkan mọ ọkan. A gba iwe titi a tun ri gba lati ọdọ awọn a r a wa lati oke-okun lori enia-kika (census) yi. Họwu ! Kilo de?

## Amodi Ile

ỌRỌ WA di ọrọ ẹnyin ara wa nisisiyi o, nigbati nwọn ri nwọn fẹ tun wa ka yi a fi alajọbi bẹ ẹnyin iya wa, ẹ jọwọ ẹ jẹ ki nwọn ko ka yin tọmọ ọ w ọ tọmọ ọwọ ; ẹ ma sọ wipe ẸNITI O BA KA MI KA IGBA IYA RẸ, nitotoripe aṣa awa YORUBA niyẹn.

Ara ile ẹni ni mọ ọ n i amodi arun n i ara i t a pee. Iyoku di ọwọ yin o !

# Barika De Sala!

Ọrọ ti a kọ leri wosika wa ọsẹ yi kiṣe ede ti o ṣe ajoji fun nyin, ede ti awọn ara wa Hausa ma nfi ki ara wọn bi ọdun ba dun ba wọn lorile aiye niyẹn, ede na ni a o si lo lati fi ki ẹnyin ọkawe wa wipe ẹ ku ọdun Awẹ ti ẹ pari ninu ọsẹ yi.

## Bisimilai

ANIYAN Bisimilai ni ọpọlọpọ wa fi bẹrẹ Awẹ-gbigba na pẹlu ọkan wipe ki awọn pari rẹ pẹlu ALHAMUDU LILAI; ogunlọgọ ni nwọn si ti di ara–ọrun laisin oṣu kan na nitoripe a ko kadara wọn nigi awọn ti yio ba wa pari rẹ.

Ṣe ẹnyin na wa ri wipe awa ti a ri ọjọ oni tiwa tayọ ?

## Alhamudu Lilai

Nitona bi a ba ti nyọ ayọ ọdun na ki a ma yọ ni ayọ ayọju, ki a ma riran awọn ọmọ ORUKAN, awọn talaka ti ko ri onjẹ jẹ bi tiwa ati awọn ti ko ri aṣọ wọ sorun bi tiwa, ki a si ṣe anu fun wọn nitoripe ẹsin alanu ni ẹsin Musulumi ko ṣe nwọn ni nkirun, mo kirun, nwọn ni ngba awẹ mo gba awẹ ti ọpọlọpọ wa mọ ẹsin Imale si lọjọ oni.

A ki yin, ẹnyin ara wa, ẹ ku ọdun, Anabi ko ṣe ọdun na ni abo ọdun fun wa.

# Iwe Si Olotu

## Mo Gbadun Iwe Alufa Atilade

Olotu, Ọpọlọpọ a w ọ n enia ọmọ ile Yoruba n i nwọn ko mọ Yoruba ka. Nwọn ko si mọ ọ kọ. Ṣugbọn nwọn le ka ede Gẹẹsi, nwọn si le kọ ọ. Eyi jẹ aṣa ti o yani lẹnu. "Ile ni a ti nko ẹṣọ r e ode". O tọ, o si yẹ ki a mọ e d e iya wa yekeyeke ki a to mọ ede ilu ajoji.

Ede Yoruba dara, o s dun pupọ bi oyin. O kun fun ọgbọn ati laakaye. O si kun fun ẹkọ pupọ. Ẹkọ ti o wa ninu iwe Yoruba dara pupọ o si ṣe ni, n i anfani ju wura ati fadaka lọ.

Nigbati mo ka awọn iwe Yoruba – a p a kini, apa keji ati apa kẹta – awọn iwe l'ede Yoruba ti Alufa E.A. Atilade ṣe, mo gbadun wọn pupọ. Mo si ri ẹkọ oniyebiye kọ n i n u wọn p u p ọ. Irufẹ i w e wọnyi d a r a pupọ f u n awọn ọmọ ti nwọn nkẹkọ lati ma a ka wọn.

Mo fun awọn o b i l'ọkunrin l'obinrin ni imọran lati ma a jeki ọmọ wọn ko ede ilu wọn a ni ede Yoruba yeke eke Yio si se awọn oluko ati awọn akẹkọ paapa ni anfani bi nwọn ba le ma a ka awọn iwe na ti alufa Atilade eninure ṣe.

Eko

Emi ni,
Alhadji Y.A. Disu
B.C.D.

lọhun "ni o " ni lati gbe oruko ti a npe ni Alhaji ati Alhaja lori. Nwọn ni iru "kunkari" ti nwọn lọ se yi "Umura" ni awọn ara ilu Mẹka alara paapa npee, sugbọn awa Yoruba lo] pe iru irin-ajo bẹ ni A-LỌ-SILẸ.

—OLOTU

## Se Alhaji Ni ?

Ni aipẹ yi ni a gbọ wipe awọn enia kan lati ipinlẹ Ijọba Ariwa ni Oke Ọya tẹle Ọlọla Alhaji Amọdu Bello, Sardauna ilu Sokoto lọ ṣe 'kukari" kan ni ilu Mẹka ati Medina.

Ẹ jọwọ, Olotu a jẹ ki ẹ la ọrọ na ye wa daradara nitoripe ọpọlọpọ ni awọn enia ti o wa larin wọn ti nwọn ko de ilu Mẹka ri ti nwọn yio tilẹ fi gun oke Arafat. Njẹ a le ma pe iru awọn e n i a layi ni Alhaji. ?

Emi ni,
Ọmọkewu

Idi Apẹ,
Abẹokuta

IDAHUN :— O ṣe p u p ọ ỌMỌ'KEWU' nigbati awa na ṣe iwadi iru ibere rẹ yi lọdọ awọn awọn agbalagba Alufa nwọn ni nitori a lọ si Mẹka kọ ni nwọn nṣe npe enia ni Alhaji, ẹniti o ba ba wọn ṣe gbogbo eto isin ti nwọn nṣe

## A Gba Fun Eleti–O

Irohin ti mo gbọ loni wipe nwọn ... wa ka kakiri ilu Nigeria nitoripe ... ka lọdun ti o lọ ko bọ si, nitu mi ... pọ lati kọ iwe yi ki nkan saara si Ọ... Ọfẹ fun gbogbo wahala rẹ ti o nje ... ero madaru ti awọn fẹ ṣe lori ... (Census) na.

Ẹ wi bẹ, nwọn si ṣebẹ, ẹ ni nwọn ... tun gbogbo wa ka ni, otitọ ọrọ ni ... we robin nsọ wọn si ni awọn ni l...
Mo igba fun yin.

jaiye,
Abẹokuta

Emi n...
J. Ajal...



Iw...

Ki...

lat...

## Ọba Adele Ni:

# A Bini l'Eko Ko Dola

## Iwa Rere Leso Enia

Ọba Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji ti ilu Eko ni gẹgẹbi on ti ma ṣe lọdọdun, on ki gbogbo ẹnyin enia on lọmọde ati lagba ti e nyọ ti ipari Awẹ wipe ẹ ku ọdun. "Nitotọ a ni lati ma ba ara wa yọ nitoriti a ba nwo nkan ti o ti rekọja lati esin wa, ti a si ari nkan gbogbo ti o nlọ lagbaiye nisisiyi, a ni lati ma ranti pe ko si on ti osan fun ẹda ju iwa rere lọ.

"Iwa rere larin ẹbi, iwa rere larin ilu ati fun agbaiye nitoripe a ko mọ initi ori mba ẹsẹ re. Ni ode ti ọjọ oni, o yẹ ki a fi han ẹnyin ara Eko pe EKO la bini si ko da owo, iwa ti a ba hu, iṣe-rere ti a ba ṣe si ara ilu ati gbogbo agbara ti a ba sa lati tun orukọ ilu wa ṣe ki gbogbo enia le ma sọrọ ilu wa na ni rere, iyẹn ni o ma nfi han pe ọmọ Eko pataki ni yin.

"Ọlọrun jẹki gbogbo yin le ma huwa rere. Ọlọrun ko ṣe ọdun yi a ni abo ọdun fun yin. Ẹ ku ọdun, ẹ ku yedun!

AYILUKA NI:

## Ara Ibadan De!

Ẹ ku ipalẹmọ itanu ọdun Awẹ Mo gbọ pe lati igbati awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ati awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọmọ ti gori aga ijọba tuntun ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni awọn ara Ibadan ti nsọ fun awọn akọda Ọlọpa Ọba wipe ki nwọn lọ wa ibikan joko si ki nwọn ye yọ awọn lẹnu lori owo-ori, alamọri owo ori ti kuro ni t'awọn. Mo gbọ wipe ọrọ ti bẹhin yọ nisisiyi nitoripe Ọgbẹni R.A. Fanikayọde tiṣe igbakeji Alakoso Ijọba Ipinlẹ na ti sọ wipe ki eku-iie sọ fun toko wipe dandan ni sisan owo ori, ati pe awọn kansilọ ilu Ibadan si ti gbe awọn alagogo jade lati lọ sọ fun ara Akanran, Moniya, Idi-Ayunrẹ ati Iyana pe ki nwọn tete ma san owo-ori wọn ki awọn akọda to de ba wọn lojiji ninu abule wọn. Dandan ni towo-ori o!

## Orisa Majidun

Abiyamọ ti o ba de eti bebe odo ti a npe ni MAJIDUN ni ọna Ikorodu ni ibẹrẹ ọsẹ yi, anu ikunlẹ abiyamọ a ṣe ẹ fun ogunlọgọ ẹmi enia lọkunrin ati lobinrin pẹlu ọmọ ọwọ ti Orisa Majidun na gba lọdun ni. Awọn ara Ipẹru mọ ODE ni orisa na pa lẹkun; Ọlọrun yio rọ yin lẹkun ara Ojowo!

A gbọ ti Orisa Majidun ti nwọn sọ wipe on ni o gun Gboyega Ṣotirẹ ti o wa moto na ni ijeje, kini o tun gun awamoto ti o da wọn nu lọna Ibinni? Tabi Orisa LARE ni?

Ẹ jọwọ, ẹ jẹki a ki lọ fun awọn dirẹba awamoto wa, ere ti nwọn nsa lọna pọ pupọ ju. Ti a ba sọ fun wọn, nwọn a wipe ki a gbẹnu wa sọnu. Idi ọrọ re o, Orisa Majidun!

## Ina Ikorodu

A tilẹ gbọ torisa Majidun ewo tun ni ti ina ti o jo loru ọganjọ ni Ikorodu ni ijarun? Ṣe ko lọwọ bamiran ninu? Ṣe ko ne wipe ẹnikan njogun kan lọwọ ni ọganjọ oru ti ko juba Ẹsu ni Ẹsa ba ba fọwọ kun? Ọna Ikorodu ni jamba itunu Awẹ gba lọdun ni: Ọlọrun ko ba wa da ọwọ rẹ duro. Ẹ ku palẹmọ ọdun Awẹ na.




ha nwa asiki funra rẹ bi?

yio pẹ lọ titi fun ọ bi o ba nfi owo pamọ

gba dẽgba nile ipamọ owo ti Barclays

Owo rẹ mbẹ labẹ abo lọwọ Barclays. Ki yio sọnu atipe bi o ti npẹ nibẹ si bẹni yio ma lọsi. Lọ bẹre nibiṣẹ Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo pamọ ki o si bẹrẹ lati ṣe bẹ ni kiakia.

"BI IWỌ BA NWÁ ASIKI FUNRA RẸ"





BARCLAYS BANK D.C.O.

# Bawo Ni Olmpio Se Ku Lori Oro Ilu Togo...?(5)

## Aiperi Wo

Ninu ọsẹ yi ni o di oṣu kan ati ọsẹ kan gbako ti mo ti bẹrẹsi se irohin bi awọn oṣelu alamulegbe wa, awọn ara ilu TOGO se bere ọrọ ilu wọn lẹhinti nwọn ti bọ loko eru awọn Oyinbo Faranse ki a run AIPERI to wọ ọrọ wọn na.

Boya e ko gbagbe itan ti mo sọ wipe Dokita Nkrumah di egungun ẹja, o si ha awọn ara ilu na lọrun nipa ọrọ ti o bẹrẹsi sọ wipe ki awọn da ilu na pọ mọ ilu Ghana. Dokita Olympio pelu awọn minisita re ti eku-ida Ijọba na wa lọwọ wọn fi aake kọri wipe ki olukuluku rin irin ẹsẹ tirẹ lọtọtọ.

Ọrọ yi bi Alakoso ilu Ghana na ninu tobẹge ti ko fi yan aṣoju (Ghana Commissioner) ilu rẹ si ilu Togo, awọn alakoso ilu mejeji ti nwọn fi ẹgbẹ kan ẹgbẹ si ni ara wọn sinu lori iwa gba were, nko gba were ti nwọn nhu si ara wọn yi.

## Ofin Pajawiri

Dokita Nkrumah bẹrẹsi mu ilu gbona fun awọn ọmọ ẹgbẹ Alatako ilu rẹ, orisirisi ofin bẹrẹsi jade nigbakugba lori awọn ti o ba fẹ tako nkan ti o nṣe. O paṣẹ wipe ki nwọn kọ ile-ẹwọn oni aja-ilẹ si igberiko kan ti nwọn npe ni Nssawam lọna Kumasi ati nibomiran.

Lẹhinti nwọn ti kọ ile ẹwọn alaja'le nwọnyi tan, o wa di wipe ki nwọn ma lọ fi iwe-agbara mu awọn ọmọ ẹgbẹ alatako ninu ile wọn loru oganjọ lọ si ọgba ẹwọn. Ọpọlọpọ wọn ni nwọn ji nibiti nwọn ti nsun lẹgbẹ iyawo wọn.

Awọn miran ti nwọn tete fura pe ọrọ a nlọ fi ni pamọ yi mbọ wa kan awọn tete fayawọ kuro ni nilu, nwọn sa gba ilu Togo ti o un mọ wọn lo lati lọ sapamọ si abẹ Ijọba Olympio. Eyi ba Dokita Nkrumah ninu jẹ pupọ.

## OJU TO RO

Awọn ẹgbẹ ọdọ (Jurento) nwọn jẹ alatako ilu Togo ko fi Olympio paapa lọrun silẹ; nwọn ni bi o ti nṣe akoso Ijọba ilu Togo na ko te awọn lọrun rara, nwọn ni o gbọgẹje fun awọnOyinbo Faranse pupọju. Awọn ọmọ ẹgbẹ alatako ni ko fo, ko niṣo.

**LATI ỌWỌ**

## Olofin Toto

Ologbe Olympio paapa ni se 'oju t... rọ ni irorẹ nso', o wa bẹrẹsi fi ofin kole-kobe gbe wọn (awọn alatako ilu tirẹ na) de mọ'lẹ. Ọrọ wa di bi o ko lọ ki o yago lọna. Awọn apakan ninu awọn ẹgbẹ na sa kuro nilu lọ si Ghana, omiran gba Dahomey lọ.

Ninu awọn ti o tete sa kuro nilu ni ỌgbẹniGrunitzky ti nwọn fi ṣe Alakoso ilu na nisisiyi. Ninu awọn ti nwọn na ni paṣan ọgba ẹwọn ni baba ẹgbẹ Juvento, Ọgbẹni Ben Apaloo, Ọgbẹni A. Santos, tiṣe asiwaju awọn ọmọ ẹgbẹ na ni ile ipbimọ aṣofin, Togo Ọgbẹni Abalo Firmin, akọwe ẹgbẹ ati ogunlọgọ awọn miran ninu ọmọ ẹgbẹ na.

## Kakuri Ni ?

Ile ọgba ẹwọn ti nwọn ko wọn lọ pamọ si ni ilu oke Togo ti nwọn npe ni Sokode dabi ọgba ẹwọn kan ti nwọn npe ni Kakuri ni oke ọya ni ilu Nigeria tiwa. Ẹnikẹni ti nwọn ba mu lọ fi pamọ sibe ti o ba fi ara rere pada sile, ki o lọ ko obi abata oloju merin ki o fi bọ ori rẹ.

Mo gbọ wipe ni aiye awọn Oyinbo Faranse ni nwọn ti kọ ile-ẹwọn yi fun awọn isansa ẹlẹwọn ti nwọn ba le, ti nwọn ko ba gba gbẹrẹ. Nwọn tun kọ iru rẹ kan si ilu ahere kan ti nwọn npe ni Mango. Gbogbo ibẹ ni nwọn si fi ofin ko awọn ọmọ alatako yi lọ fi nwọn pamọ si.

Awọn Aganyin Ghana ti nwọn sa kuro nilu wa si Togo bẹrẹsi sọ oko-ọrọ buruku ranṣẹ si alakoso Ijọba ilu na, awọn miran ti nwọn kọ sa kuro nilu, ti nwọn ri wipe Ijọba Nkrumah ko tẹ awọn lọrun qẹrẹ si fi bọmbu oloro sọ'ko sii.

## Aiye Oselu

Dokita Nkrumah fi igba kan ranṣẹ si Ologbe Olympio wipe ki o le gbogbo awọn ara ilu on ti nwọn wa sapamọ sọdọ rẹ jade, ko jalẹ, Olympio ni ofin awọn alagbara agbaiye ko wipe ki awọn ma le awọn ti o ba sa asala wa si ọdọ awọn.

Ninu nwọn nfa ọrọ yi mọ ara wọn lọwọ, ko ju ọjọ kẹwa rẹ lọ ni a gbọ wipe awọn ṣọja ilu Togo dọtẹ si alakoso Ijọba ilu wọn na, ni nwọn ba lọ fi ibọn ati agba ka a mọ'le, nwọn si pa Dokita Sylvanus Olympio.

Ẹsun ti awọn ṣọja na fi Olympio sun ni wipe ko da iṣẹ silẹ nilu, ọpọlọpọ awọn ti nwọn ti ṣe iṣẹ ṣọja ri ni nwọn nrin kiri, ti ebi npa wọn ti nwọn ko ri iṣẹ ṣe; awọn ti awọn si wa ninu iṣẹ, Ijọba na ko san owo oṣu fun awọn lasiko.

Ẹnyin ọkawe mi, bayi ni Dokita Olympio ṣe ku lori ọrọ ilu Togo. Aiye awọn oṣelu ni ẹ ri yen o ! O pari.

# Dandan Ni T'owo Ori N'ibadan

(IBADAN—Ilẹ nlọ ni Ibadan nisisiyi nipa ọrọ owo-ori (tax) ti ọpọlọpọ awọn ara Ibadan kọ ti nwọn ko fẹ san. Ninu ipade ti awọn kansẹlọ ilu Ibadan na ṣe ni Oke Mapo laipẹ yi nwọn ni awọn ko ti le ṣe eto inawo gbogbo nkan mirin-mirin ti awọn fẹ ṣe fun ilu na ninu ọdun titun ti awọn ṣẹṣẹ bọ si yi nitoripe awọn ko ti ri idaji gba ninu owo ti awọn ni lati na.

Nwọn ni ninu ọkẹ marun pọnun (£100,000) ti awọn nri kojọ lori owo ori lọdọdun awọn ko ti ri ju ọkẹ meji pọnun (£40,000) lọ bẹni nkan bi £1 million ni awọn fẹ na fun idagbasoke ilu.

Ni owurọ kutukutu ana, awọn akọda pelu ọlọpa ijọba ibilẹ ti da si arin ilu lati ma lọ awọn enia mu kakiri lori owo ori ni ilu Ibadan.

Onirohin wa ni o to irinwo (400) awọn enia ti nwọn ko ni iwe owo-ori lọwọ ti nwọn ko lọ si ori orule ni Oke Mapo. Mo gbọ wipe Ọgbẹni R A Fani-Kayọde paapa ti fi we sọwọ si gbogbo awọn kansulu Ibadan ati agbegbe wipe ki nwọn sọ fun awọn enia wọn ki nwọn tete san owo-ori ti nwọn ba fẹ ki Ijọba ṣe awọn nkan daradara si awọn adugbo olukuluku wọn.

Ọgbẹni Fani-Kayọde ni ko si ọna kan ti Ijọba le gba ri owo ju ọna ti owo ori yi lọ nitoripe Ijọba ki rọ owo ni agbẹdẹ kan rara.

# Police Dog Expert Flying To Nigeria

LONDON — A policeman who trained one of Britain's top teams of police dogs is flying to Lagos on 7th March to help build up a police dog force in Nigeria.

He is 28-year-old Constable Peter Stephenson of the Middlesbrough Police Force, and his first task in Nigeria will be to help select a team of dog handlers. He will spend three weeks in Nigeria before returning to Britain with the team for training, probably with the Metropolitan Police in London.

The training course in Britain will last for about a month, after which Constable Stephenson will return to Nigeria with the team to take up an appointment as Assistant Superintendent. His wife and two sons will go will go with him.

Constable Stephenson was responsible for training the Middlesbrough police dogs when they won the British National Police Dog trials in Britain in 1961.

## Nigeria Judge Elected Fellow Of University College

LONDON — Sir Vahe Bairamain, a Federal Justice of the Supreme Court of Nigeria, has been elected a fellow of University College, London.

Sir Vahe was a student at the college from 1919 to 1922, during which time he studied classics, wi..ning several scholarships and and prizes. He was called to the English Bar in 1923 at the Middle Temple.

The title of Fellow is awarded to old students of the college "who have subsequently attained distinction in arts, science, literature and public affairs."

A REJOINDER:

## Chief Akintola Not Booed

The following letter wa received from Mr Taju Thompson in conection with a news item which was published in a local daily the other day: "There was a piece of news item in the "Daily Express" of 19th Inst. that Chief S L. Akintola, the Premier of the Western Region was booed when he paid a friendly visit to few of his supporters in Lagos.

"The fact of the case was that the Chief during the vist to the persons named in the report was warmly welcomed by his supporters and well-wishers in the Ward as well as other admirers who expressed great pleasure in having the chance to meet the Premier in person and also having the opportunity to shake hands with him.

"There was nothing like booi..g or jeering.

Yours faithfully,

Taju Thompson"

**"ELETI—OFE"**

**Is yours, Read it and advertise your goods in it.**

Comfortable and safe



A roomy 5-6 seater, space for lots of luggage, luxurious appointment, excellent finish, a very high standard of safety: these and many other welcome features you find in both of the 190 models and besides the 190 Diesel offers quite exceptional economy. Let us demonstrate by a trial run, free of any obligation, what excellent value these cars represent.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (E.B.). IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORTH-ARCOURT: ABA

Sub—Distributors:

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY: ONITSHA: ABA.

## Ara Togo Fe Se Ipade Idibo

(O bere loju ewe kinni)

Şaju eyi mo gbọ irohin kan wipe awọn ṣoja beresi kanramọ awọn ọmọ Nigeria ti nwọn ngbe ibẹ, nwọn ni nitori ti awọn alakoso Ijọba Nigeria ti nwọn ni awọn nṣe iwadi (ẹnkuari) iku ti o pa Dokita Olympio ni. Nwọn ni alayọnusọ ni awọn olotu Ijọba Nigeria na ko si eyiti o kan wọn nibẹ. Ọpọlọpọ awọn ara Nigeria na ni nwọn ti nsa lọ si ilu PORTO—NOVO lori ọrọ na.

A gbọ wipe alamojuto tuntun Ijọba Togo na, Ọgbẹni Nicholas Grunitzy ti pe awọn olori awọn ṣoja na, o si mbẹ wọn lẹbẹ ki nwọn mu suru, ki nwọn jẹki awọn ajoji orilẹ-ede yi ṣe iwadi ti nwọn fẹ ṣe na.

## Nkrumah Ranse Si Belewa

Irohin kan ti a tun gbọ lana ni ti Minisita ilu Aganyin kan, Ọgbẹni A K Puplampu ti Dokita Nkrumah, alakoso ilu Ghana fi iwe kan ran nişẹ si Alhaji Tafawa Balewa, Alakoso Ijọba ilẹ yi ati Gomina agba Dokita Azikiwe lori ọrọ awọn ilu Afrika ati ọna ti awọn le gba lori gbogbo segesege ti nkan lọ yi, ṣugbọn a ko ti gbọ esi ti nwọn fun un lori iwe rẹ na.

Irohin ti tan kalẹ ni Accra ati Kumasi wipe Dokita Nkrumah na fẹ ran ikọ lọ si ipade nla ti nwọn fẹ ṣe ni aipẹ yi ni Abyssinia. O ni on ko fẹ ki nwọn ti oju on yan on ni'ẹbọ rara; O ni ilu on na ni imọran ti awọn le fun wọn nibi ipade nla na.

## Ara Korokun

Awọn agba oşelu ni ọrọ Dokita Nkrumah alara paapa ṣẹ nsu u, on na ṣẹṣẹ wa mọ wipe agbajọ ọwọ ni a fi nsọ aiya. A gbọ wipe o ti fi iwe ranṣẹ si awọn alakoso ilu miran ni ilu Afirika kakiri nipa ọrọ yi kanna. Ọrọ na wa di ara ko rọ okun, ara ko rọ adiẹ.

## Olotu Ijoba Dahomey Wa S'Eko

Cotonon, Dahomey—
Hubert Maga, Olotu Ijọba ilu Dahomey sare wa s'Eko ni irọlẹ ana lati ba Alhaji Tafawa Balewa, alakoso Ijọba Nigeria sọrọ. Ikẹja ni awọn oşelu mejeji ti pade sọrọ, ko si ẹniti o mọ nkan ti nwọn jọ sọ ki Maga to pada si ilu rẹ lẹsẹkanna.

## Oloye Oluwa Ki Yin

(O bere loju ewe keji)

Oloye Oluwa ni o yẹ ki a mọ ṣe iranti wipe ifẹ ni ẹsin Imale kọ gbogbo wa, ki a si fi ifẹ na fa ara wa mọra, ki a ye fi oro san oro fun ara wa.

Ẹnyin ara Eko, mo bẹ yin, ki ẹ fa ara yin mọra, ki ẹ si mọ fi ẹkọ-ilewe awọn ọmọ yin jafara rara. Ile-iwe ile-ọgbọn ni. Lẹkansi, mo ki nyin, ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun, a ṣeyi ṣamọdun.




## "Ote Imale Ta Ju Koko"

(O bere loju ewe kinni)

Sugbọn ọrọ kan bọ si AYILUKA "ELETI-ỌFẸ" leti loru ana wipe ọtẹ miran tun fẹ bọ silẹ larin Eko lori ọrọ Musulumi ilu Eko lori ọrọ Mọşalaşi Jimoh kanna yi. Irohin ti AYILUKA wa na gbọ ni wipe lati nkan bi oşu mẹfa sẹhin ni ede-aiyede kan ti wa larin awọn alamojuto eto Mọsalasi na, ti o fi di wipe nwọn npe ara wọn lejọ si Kotu-ganran, Iwe ẹjọ na si wa ni Kotu nisisiyi.

Mo gbọ wipe awọn agbalagba, awọn bi Balogun gbogbo ilu Eko ati awọn saraki ilu ti fẹsẹ bọ sokoto lati tẹ ina ọtẹ na pa bamu-bamu.

## Nigerian Ports Authority

### INVITATION TO TENDER

### SALE OF FEROUS MATERIALS — PORTHACOURT

### SIX — MONTHLY

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period up to and including 30th June, 1963, in the Authority's Dockyard and Quays at Port-Harcourt or any other particular point where the Authority may have scrap materials for disposal in the Port Harcourt area.

2. A copy of the Tender Form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, and the Port Manager, Eastern Ports, Port-Hacourt, on payment of a deposit of £5 to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays, Lagos, and the Area Accountant, Port Harcourt Quays. The completed Tender Form should thereafter be returned to the Secretary, irrespective of where the form has been obtained, in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL - TENDER FOR SCRAP" so as to reach him not later than Tuesday, March 12th 1963.

3. The deposit of £5 will not be refunded in any event to any tenderer, who, upon being advised of the acceptance of his tender, fails to pay for and to remove the materials made available.

4. Tenderers are warned that scrap available for disposal may comprise both ferrous and non-ferrous materials although it is expected that most of the materials will be ferrous.

5. During the period indicated above, the successful tenderer will be required to remove, at his own expense, whatever scrap si made available for sale (with the exception mentiond above) within 7 days of being notified to do so. He will also be required to make necessary arrangements at his own expense for all such scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority before being removed.

6. The Authority reserves the right to resell any materials not removed by the purchaser after 7 days of payment of purchase price, and such purchaser shall forfeit such payment in the event of such non-removal.

7. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice, NO. 358.

20th February 1963.

Printed and Published by The Union Printing & Publishing Company 28, Kosọkọ Street Phone 23370 Lagos
Editor (Olotu) Ọla. Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.